Njinga & Sepé: Revista Internacional de Culturas, Línguas Africanas e Brasileiras
São Francisco do Conde (BA) | vol. 5, nº Especial I | p. 61-70 | jan./ jun.2025.

# Ojúṣe èrò ìwòran nínú àgbéjádé lítíréṣọ̀ alohùn yorùbá

# O papel da imaginação visual no desenvolvimento da literatura oral iorubá

**Ọmọlayọ̀ Dúrótadé ÒGÚNLỌLÁ, (Ph.D)** *
ORCID iD https://orcid.org/0000-0002-0546-8986

**ÀṢAMỌ̀**
Lítíréṣọ̀ alohùn ilẹ̀ Áfíríkà ti wà kí ètò ẹ̀kọ́ ilé-ìwé tó dé, èyí kò sì yọ àwọn Yorùbá ní Gúsù ìwọ̀ Oòrùn ilẹ̀ Nàìjíríà sílẹ̀. Yorùbá ti ní wọ́n sì tún ní ohun tí a lè pè ní àṣà àti ìsẹ̀ṣe tí a mọ̀ wọ́n mọ̀. Èyí ni a lè pè ní lítíréṣọ̀ tiwọn èyí tí wọn ń tàn ká nípasẹ̀ ọ̀rọ̀ ẹnu láti ìran kan sí èkejì tó sì kún ojú òṣùwọ̀n fún lílò láti rí i dájú pé àlàáfíà jọba láàrin wọn àti fún ìdàgbàsókè àwùjọ wọn. Ọ̀kan lára lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá ni ewì alohùn Yorùbá. Apilẹ̀kọ yìí ń ṣàgbéyẹ̀wò iṣẹ́ àwọn akéwì/apohùn, òṣèré, pàápàá jù lọ ipa èrò ìwòran lórí àgbéjáde lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá. Lára èròǹgbà iṣẹ́ àpilẹ̀kọ yìí ni: láti fi ojú láměyítọ́ wo ipa àwọn èrò ìwòran nínú gbígbékalẹ̀ lítíréṣọ̀ alohùn; latí wo ànfààní tàbí àlébù ipa tí a ń wí yìí lórí oníṣẹ́ ọnà fúnrarẹ̀, èrò ìwòran àti àwùjọ lápapọ̀; A fi lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá ṣe ìtìsẹ̀ wa. Àwọn iṣẹ́ àpilẹ̀kọ díẹ̀ ti wà tí a lè tọ́ka sí lórí kókó ọ̀rọ̀ yìí. Lára wọn ni ti Àkàngbé (2021) àti Akínyẹmí (2012). Àwọn méjèèjì ló sọ̀rọ̀ léréfèé lóri ipa èrò ìwòran nínú àgbéjáde lítíréṣọ̀ àtẹnuwí. Àwọn wọ̀nyí ni a fi ṣe àtẹ̀gùn tí a sì wo orí ọ̀rọ̀ náà ní àwòfín. Aṣèwádìí ṣe àmúlò ọgbọ́n ìwádìí "ṣé kí n rí i" nípa síṣe alábápín ọdún egúngún ní ìlú kan ni ìpínlẹ̀ Kwara, kíkó àwọn ìpéèrẹ̀ jọ fún eré àló, wíwo eré síṣe lọ́kan-ò-jòkan lórí ìtàgé àti nínú Sinnimọ́. Iṣẹ́ ìwádìí yìí sàmúlò tíọ́rì sosiọ́lọ́jì èyí tó ní ṣe pẹ̀lú ìbágbépọ̀ ara ẹni ní àwùjọ. A lo tíọ́rì yìí ní ìbámu pẹ̀lú ìgbàgbọ́ pé asàfihàn àwùjọ ní lítíréṣọ̀. Fún ìdí èyí, a ní èrò láti fihàn pé gbogbo ohun tí òṣèré, akéwì, apohùn ń gbé jádé ní ṣe pẹ̀lú àwùjọ. Àpilẹ̀kọ náà gúnlẹ̀ pé àwọn èrò ìwòran ní ipa pàtàkì láti kó nínú àgbéjáde lítíreṣọ̀ alohùn. Wọ́n ní ipa pàtàkì láti kó nínú àṣeyọrí tàbí ìkùnà akéwì, apohùn tàbí òṣèré. Ìdí nìyí tó fi ṣe pàtàkì láti fi wọ́n sí aàyè tó tọ́ sí wọn. Lára èròǹgbà iṣẹ́ ìwádí yìí ni láti jẹ́ kí a mọ̀ pé kìí ṣe wíwà ní ìkàlẹ̀ èrò ìwòran ló ṣe pàtàkì bí kò ṣe ipa wọn lóri àgbéjádé iṣẹ́ lítíréṣọ̀ alohùn.

**KÓKÓ Ọ̀RỌ̀**
Ojúṣe, Èrò Ìwòran, Lítíréṣọ̀, Yorùbá

**RESUMO**
A literatura oral africana existia antes do advento do sistema escolar, e isso não excluiu o povo iorubá do sudoeste da Nigéria. Os iorubás têm e ainda têm o que pode ser chamado de seus próprios costumes e práticas. Isso pode ser chamado de sua própria literatura, que eles espalharam por meio da transmissão oral de uma geração para outra e que é suficiente para garantir a paz entre eles e para o desenvolvimento de sua sociedade. Uma das formas de literatura oral iorubá é a poesia oral iorubá. Este artigo examina o trabalho de poetas/narradores, atores e, especialmente, a influência do teatro no desenvolvimento da literatura oral iorubá. Os objetivos deste artigo são: examinar criticamente o papel dos conceitos visuais no desenvolvimento da literatura oral; examinar os benefícios ou desvantagens dessa influência sobre o próprio artista, o conceito visual e a sociedade como um todo; e usar a literatura oral iorubá como ponto de partida. Existem alguns artigos que podem ser citados sobre este tema. Entre eles estão os de Ákangbé (2021) e

* E-mail: ogunlola.od@unilorin.edu.ng

Akínyêmí (2012). Ambos discutiram brevemente o papel dos conceitos visuais no desenvolvimento da literatura oral. Estes são usados como um trampolim e analisamos o tópico sob uma perspectiva. O pesquisador utilizou o método de pesquisa "deixe-me ver" participando de uma comunidade de 10 anos em uma cidade no estado de Kwara, coletando amostras para uma peça e observando apresentações no palco e no cinema. Este trabalho de pesquisa utilizou a teoria sociológica, que trata da interação social dos indivíduos em sociedade. Essa teoria foi utilizada de acordo com a crença de que a sociedade é um reflexo da literatura. Portanto, pretendemos mostrar que tudo o que um ator, poeta ou escritor produz está relacionado à sociedade. O artigo conclui que as ideias do público desempenham um papel significativo na produção de obras literárias. Elas desempenham um papel significativo no sucesso ou fracasso de um poeta, escritor ou ator. Por isso, é importante dar a elas o devido lugar. Parte do propósito desta pesquisa é nos fazer perceber que não é a presença de ideias visuais que importa, mas sim o seu papel no desenvolvimento de obras literárias.

**PALAVRAS-CHAVE**
Ojuse, Ideias Visuais, Literatura, Iorubá

## Ìfáárà

Ilẹ̀ Áfíríkà lápapọ̀ àti ní pàtàkì jù lọ àwọn ẹ̀yà Yorùbá tó wà ní gúsù ìwọ̀ oòrùn ilẹ̀ Nàìjíríà ní ìlànà ìgbé ayé wọn èyí tí a lè ṣàfihàn nínú lítíréṣọ̀ wọn. Finnegan (1968) sọ pé:

> *In the traditional Kingdoms of Africa, Poets were attached to the courts of powerful kings, to the Nobles or lesser chiefs, and to all those who had pretensions to honour and thus to poetic celebrations in their society". The ruling Monarchs and their Ancestors were glorified in poems and real and ideal deeds were attributed to them in lofty and effective language.*
>
> Ní àwọn ìjọba ìbílẹ̀ Áfíríkà, wọn a máa yan àwọn akéwì sí ààfin àwọn ọba alágbára, àwọn ọba tó nípò, àti àwọn ọ̀tọ̀kùlú tàbí ọ̀jẹ̀ wẹ́wẹ́ olóyè, àwọn gbajúmọ̀ àti àwọn ìjòyè pẹ́ẹ́pẹ̀ẹ̀pẹ́ pẹ̀lú gbogbo àwọn tó bá yẹ kí wọn bu ọlá fún. Wọn a máa yin ọba àti àwọn ìran tàbí babańlá wọn nínú ewì wọn a sì máa fi èdè tó dùn gbóríyìn fún ohun ribiribi tí wọ́n ti ṣe.

Yàtọ̀ fún èyí, àwọn akéwì, apohùn tàbí òṣèré tún ní ojúṣe mìíràn bí i fífi ìtàn pamọ́, èyí sì máa ń jẹ́ apákan iṣẹ́ ọnà wọn. Àwọn kan tilẹ̀ gbà pé èyí ṣe pàtàkì nínú iṣẹ́ ọnà wọn. Àwọn èrò ìwòran sábà máa ń jẹ́ àwọn ènìyàn tí wọ́n máa ń pésẹ̀ síbi ayẹyẹ lọ́kan-ò-jọ̀kan láàfin ọba.

Àkàngbé (2021) sàlàyé pé:

> *Oral performance is a vital constituent of the socio-cultural life of Africans as it manifests itself in varying forms – poetry, song, oral narratives, proverbs, riddles, jokes, etc. in virtually every aspect of their lives: cultural, spiritual, social and occupational. Verbal art, as it is called, is therefore highly regarded and revered among them.,,,,As a matter of fact, oral performance is an inseparable aspect of lives of Africans.*
>
> Àgbéjáde ìtagbangba jẹ́ abala kan pàtàki lára ìgbé ayé àwọn ènìyàn Áfíríkà gẹ́gẹ́ bí ó ṣe máa ń farahàn ní oríṣiríṣi ọ̀nà bíi – ewì, orin,

ìbánikẹ́gbẹ́, iṣẹ́ síṣe. Lítíréṣọ̀ àfẹnusọ jẹ́ ohun tí wọ́n kárámásìkí láàrin wọn. Òtítọ́ ibẹ̀ ni pé àtẹnusọ (gbígbéjáde) lítíréṣọ̀ alohùn kò ṣeé yà sọ́tọ̀ kúrò lára ìgbé ayé àwọn ènìyàn Áfíríkà

Ó tèsíwájú pé ó jẹ́ orísun ìdárayá, ìkéde àti ìpolongo àṣà àwùjọ wọn. Fún ìdí èyí àwọn èrò ìwòran tí òṣèré ń ṣeré fún kò wà ní ìkàlẹ̀ lásán, ó ní ipa pàtàkì tí wọn ń kó nínú gbígbéjáde lítíréṣọ̀ alohùn tí a ń sọ̀rọ̀ rẹ̀ yìí.

Nínú àgbéjáde lítíréṣọ̀ alohùn àwọn èrò ìwòran jẹ́ alábàṣiṣẹ́pọ̀ àti orísun ìtumọ̀. Wọ́ kìí ṣe olùtẹ́tísí lásán bí kò ṣe akópa tó ń ṣe àtúnrọ ìrírí òṣèré nípaṣẹ̀ fífi etí sí eré, dídásí eré, àti fífún eré ní ìtumọ̀. Kíkópa àwọn èrò ìwòran lè ní ipa lórí àgbéjáde òṣèré fúnrarẹ̀ tí yóó sì mú kí òṣèré ṣe àtúnṣe tó bá yẹ.

Kí ẹ̀kọ́ ìwé (mọ̀-ọ́n-kọ, mọ̀-ọ́n-kà) tó dé ni lítíréṣọ̀ alohùn ti wà láwùjọ Yorùbá. Gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ, ní alẹ́, lẹ́yìn iṣẹ́ òòjọ́, àwọn àgbà ilé lọ́kùnrin àti lóbìnrin á kó àwọn ọmọdé jọ láti sọ oríṣìíríṣìí ìtàn fún wọn. Ó lè jẹ́ ìtàn àlọ́, ìtàn orírun, ìtàn ìwáṣẹ̀ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Kókó èròǹgbà púpọ̀ nínú ìtàn tí a ń wí yìí ni láti gbin ẹ̀mí ìwà ọmọlúàbí sí àwọn ọmọdé lọ́kàn. Ẹ̀yà Yorùbá ka ìwà ọmọlúàbí sí púpọ̀. Kò sí ohun tí ènìyàn lè jẹ́ tàbí tí ó lè dà láyé, láìsí ìwà ọmọlúàbí, irú ẹni bẹ́ẹ̀ kò ní aàyè láwùjọ. Akéwì Alohùn Yorùbá kan ló kéwì pé:

Ẹni tó lówó tí ò níwà
Owó Olówóló ní
Ẹni kọ́lé tí ò níwà
Ilé onílé ló kọ́
Ẹni láya tí ò níwà
Aya aláya ló ní (àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀lọ)

Kókó yìí jẹ́ ohun tí púpọ̀ nínú lítíréṣọ̀ Yorùbá máa ń fẹnubà. Nínú àṣà Yorùbá, ení tí kò ní ìwà ọmọlúàbí kò lè di ipò tó dára mú láwùjọ. Kódà Yorùbá máa ń ṣàkíyèsí ìwà ọ̀gá iṣẹ́ kí wọn to fi ọmọ sí ẹnu ẹ̀kọ́ṣẹ́. Ṣugbọ́n èyí kọ́ ni ohun tí a fẹ́ gbé yẹ̀wò nínú àpilẹ̀kọ yìí. ohun tó jẹ wá lógún ni láti wo ipa èrò ìwwòran nínú àgbéjáde lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá.

Lára lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá ni àlọ́, ìtàn orírun, ìtàn ìwáṣẹ̀, ìtàndòwe, òwe, oríkì, Iwì/ẹ̀sà egúngún, ìjálá aré ọdẹ, ẹkún ìyàwó, eré-oniṣe (eré orí ìtàgé) àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. A lè pín ewì alohùn Yorùbá sí ìsọ̀rí mẹ́ta báyìí: ajẹmọ́rọ̀ ẹnu, ajẹmọ́'sàre àti ajẹmórin. Ìgbéjáde, ibi ìṣeré, irú èrò ìworan àti èròǹgbà wọn yàtọ̀ sí ara wọn.

Gbígbéjáde lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá dá lórí òṣèré tí yóó ṣe àtòjọ rẹ̀ fún ayẹyẹ kọ̀ọ̀kan. Finnegan (1968) gbà pé tí kò bá sí gbígbéjáde lẹ́nu nípasẹ̀ ọ̀kọrin tàbí sọ̀rọ̀sọ̀rọ̀, iṣẹ́ lítíréṣọ̀ tí a kò kọ sílẹ̀ kò lè lọ fún ìgbà pípẹ́. Ó tẹ̀ síwájú láti sọ pé:

> *The significance of performance in oral literature goes beyond a mere matter of definition for the nature of the performance itself. It makes an important contribution to the impact of the particular literary form being exhibited. (pp.1-2).*
>
> Pàtàkì iṣẹ́ lítíréṣọ̀ alohùn kọjá kí a kàn fún un ní oríkì nípa ọ̀nà ìgbéjáde rẹ̀ lásán. Ó ní ipa pàtàkì tó ń kó lóri irú iṣẹ́ ọnà tí a ń gbé jáde. (o.i.1-2).

Abímbọ́lá (1975, o.i.807) sọ pé:

> *It is probably a truism to say that the real nature (the true quality) of a piece of oral poetry can only be realized in performance, indeed there can hardly be an alternative to it".*
>
> Bóyá a lè sọ pé òtítọ́ tí kò mú àríyànjiyàn lọ́wọ́ ni kí a sọ pé ìṣẹ̀dá ewì alohùn kan ni a lè mọ̀ nípasẹ̀ bí a ṣe ṣe é (bí a ṣe gbé e jáde), b'óyá ni a lè lo ìlànà mìíràn.

Èyí túmọ̀ sí pé lítíréṣọ̀ alohùn, pàápàá ewì alohùn máa ń ṣe àgbékalẹ̀ ọ̀nà ìgbéjáde. Ohun tàbí ayẹyẹ tí a bá fẹ́ lò ó fún àti èròǹgbà rẹ̀ ló sábà máa ń sọ èyí. Àfojúsùn àpilẹ̀kọ yìí ni láti wo ipa èrò ìwòran nínú ìgbéjáde lítíréṣọ̀ alohùn nípa fifi àwọn lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá ṣe òdiwọ̀n.

## Ìṣe gẹ́gẹ́ bí àbùdá lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá

A lo '**ìṣe**' láti ṣàpèjúwe òye àti ẹwà iṣẹ́ lítíréṣọ̀ kan àti gbígbéjáde rẹ̀. Ẹ̀ya lítíréṣọ̀ alohùn ni yóó sọ ohun tí àkóónú rẹ̀ yóó jẹ́. Bí àpẹẹrẹ, àkóónú iwì egúngún yàtọ̀ sí ti ẹkún ìyàwó, bákan ńà ni ti ẹkún ìyàwó yàtọ̀ sí ti rárà. Èyí wà ní ìbámu pẹ̀lú ìpèdè Yorùbá kan tó sọ pé "a kì í kọrin ọ̀fọ̀ níbi ayẹyẹ ìgbéyàwó".

Ó tún ṣe pàtàkì láti fi kún un pé ẹ̀yà lítíréṣọ̀ alohùn tí a fẹ́ gbé jáde ni yóó sọ irú ìmúra òṣèré tàbí apohùn. A lè fi aṣọ tí òṣèré kan bá wọ̀ mọ irú lítíréṣọ̀ alohùn tó fẹ́ ṣàfihàn rẹ̀. Bí àpẹẹrẹ, G**bèrí** ni aṣọ eré asùnjálá, nígbà tí egúngún máa ń wọ **Ẹ̀kú** gẹ́gẹ́ bí aṣọ eré rẹ̀. Àwọn kan a máa pè é ní **Àgọ̀**.

Bákan náà ni ọ̀kọ̀ọ̀kan wọn ní ohùn tí a fi ń gbé wọn jáde. Bí àpẹẹrẹ, nítorí Yorùbá gbàgbọ́ pé láti ọ̀run ni àwọn egúngún ti wá, wọn a máa yí ohùn wọn padà sí ríran lẹ́nu lati fi ìdí ìgbàgbọ́ yìí múlẹ̀. Ní ti ẹkún ìyàwó, wọn kì í yí ohùn wọn padà.

Díẹ̀ lára ohun tí òṣèré gbọ́dọ̀ ṣe láti ṣe àṣeyọrí nìwọ̀nyìí:

(i). Ó gbọ́dọ̀ rí ara rẹ̀ ní gbogbo ìgbà kí ó mọ ibi tí òun mọ àti ìwọ̀n tí òún wọ̀n. Ó gbọ́dọ̀ mọ ìdí tí àwọn èro ìwòran fi wà ní ìkàlẹ̀ láti tẹ́tí sí ohun tí ó fẹ́ sọ àti ọjọ́ orí olúkúlùkù wọn.

(ii). Ó gbọ́dọ̀ máa fi ara balẹ̀ ní gbogbo ìgbà kí ó rí àwọn èrò ìwòran bí ọ̀rẹ́, kí ó sì tún máa bá wọn sọ̀rọ̀ bí ọ̀rẹ́.

(iii). Ó gbọ́dọ̀ mọ àwọn èrò ìwòran rẹ̀ dáadáa àti ohun tí wọ́n nífẹ̀ẹ́ sí, kí ó sì fi àkóónú iṣẹ́ rẹ̀ sọ
orí ìfẹ́ àwọn.èro ìwòran.

(iv). Ó ṣe pàtàkì láti dánrawò (gbáradì) ṣáájú àkókò eré.

(v). Ó ṣe pàtàkì kí ó kọ́ bí a ṣe ń fi nǹkan kọ́ra, kí ó sì lè ṣe àtúnṣe tó dá lórí ìmọ̀sílára tí àwọn èrò ìwòran bá fi hàn.

## Lítíréṣ̀ọ Alohùn Yorùbá

Àwọn olùgbọ́ tàbí olùtẹ́tísí eré ni a ń pè ní èrò ìwòran. Àwọn ni ọ̀kọrin àti onílù bíi ti inú iwì tàbí ẹ̀sà egúngún, àwọn ọmọ ẹ̀kọ́ṣẹ́ lọ́kùnrin àti lóbìnrin àti àwọn mìíràn tó bá ní ìfẹ́ sí i. Ní ti egúngún agbégijó, àwọn onílù lè ní ẹgbẹ́ tí wọ́n fi ìmọ̀ ṣọ̀kan. Wọ́n á ni olórí tí olukúlùkù wọn sì ní ohun tí a mọ̀ ọ́n mọ̀. Àwọn onílù lè má jẹ́ ẹbí kan náà pẹ̀lú ẹni tó ń pohùn tàbí tó ń ṣeré, ṣùgbọ́n wọ́n gbọ́dọ̀ ní àjọṣepọ̀ pẹ́kípẹ́kí pẹ̀lú ẹni tó ń ṣeré. Bí àwọn onílù wọ̀nyì ṣe ń lùlù sí orin a máa ran ìrònú òṣèré lọ́wọ́; èyí sì máa ń fún wọn ní ìwúrí láti ṣe àṣeyege.

Ipa tí èrò ìwòran ń kó nínú eré ṣe pàtàkì púpọ̀, bí kò ṣe lè sí ilé ìjọsìn tí kò bá sí olùjọ́sìn, bí kò ti lè sí olùkọ́ láìsí akẹ́kọ̀ọ́, bẹ́ẹ̀ gẹ́gẹ́ ni kò lè sí ìṣe lítíréṣọ̀ alohùn láìsí èrò ìwòran. Bí àwọn olùjọ́sìn ṣe ń mú ilé ìjọ́sìn dùn, bẹ́ẹ̀ ni àwọn èrò ìwòran ń mú kí àgbéjáde lítíréṣọ̀ alohùn dùn. Alájùmọ̀ṣe ni èrò ìwòran. Asọ̀tàn tàbí òṣèré ni yóó kọ́ àwọn èrò ìwòran, yóó mú ìwúrí bá wọn, yóó pa wọ́n lẹ́rìn ín. Èyí túmọ̀ sí pé èrò ìwòran ni yóó gbádùn eré ọ̀hún jù lọ. Lọ́nà kan, wọ́n ní àǹfààní láti lo àkókò ìsinmi wọn dáadáa. Lọ́nà mìíràn ẹ̀wẹ̀, àsìkò náà jẹ́ àsìkò ìdárayá, ìmúnúdùn àti pẹ̀lú pé àǹfààní wà fún wọn látí ní àjọṣepọ̀ pẹ̀lú ará, ọ̀rẹ́ àti ojúlùmọ̀.

Èrò ìwòran ni ọ̀kọrin tàbí elégbè fún orin tí òṣèré bá kọ. Èyí hànde púpọ̀ nínú iwì àti ẹ̀sà egúngún. Lẹ́yìn ẹ̀sà pípè, (iwì kíké), egúngún yóó ké sí èrò ìwòran (elégbè) rẹ̀, yóó sì bèèrè bóyá wọ́n ṣetán láti gbe orin tí òun fẹ́ kọ. Yóó sọ bayìí pé:

**Egúngún:** *Elégbè mi Elégbè òrìṣà*
**Elégbè/Èrò Ìwòran:** *Eégún Aláré*
**Egúngún:** *Ẹ kú eré elégbè mi òkun bí ẹni pe omi, ọ̀sà bí ẹni pe odò dábọ̀*
**Elégbè/Èrò Ìwòran:** *Eégún ọlọ́lá*
**Egúngún:** *Ẹ̀ẹ́ gberin àbẹ́ ò gberin?*
**Elégbè/Èrò Ìwòran:** *À á gberin.*

Ó ṣe pàtàkì láti rán wa létí pé àwọn egúngún ti máa ń dé sí ìlú tí wọ́n ti fẹ́ ṣe ayẹyẹ ọdún egúngún, ó pẹ̀ jù, ọjọ́ márùn ún sí ọjọ́ tí ayẹyẹ yóó bẹ̀rẹ̀. Wọ́n a ti fi imú fínlẹ̀, wọ́n á ti rí àwọn ọmọ ìlú tí yóó ta wọ́n lólobó àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ tó ṣẹ̀ ní ìlú tàbí ní agbègbè láìpẹ́ ọjọ́; yálà èyí tó dára tàbí èyí tí kò dára, gbogbo rẹ̀ ni wọ́n á fi kọrin tí wọ́n bá dé agbo eré.

A tún gbọ́dọ̀ fi kún un pé láyé àtijọ́, àkọmọ̀nà àwọn akéwì, ọ̀kọrin àti òṣèré ni pé "N ó wìí, ọba kan kì í pọ̀kọrin". Ìtumọ̀ èyí ni pé ọ̀kọrin ní ẹ̀tọ́ láti bu ẹnu àtẹ́ lu ẹni yòówù tó bá hùwà to lòdì sí èyí tí àwùjọ ń fẹ́, ipò yòówù kí irú ẹni bẹ́ẹ̀ wà láwùjọ, wọn a sì máa gbóríyìn fún ìwà tí àwùjọ ń fẹ́. Wọ́n a máa ṣe àtòjọ orin lọ́kan-ò-jọ̀kan yálà láti tako ìwà tí àwùjọ kọminú sí tàbí láti gbóríyìn fún ìwà tí àwùjọ yàn láàyò. Bí àpẹẹrẹ, ẹni tó lọ jí iṣu ẹlòmiíràn wà, wọ́n á kọrin bú irú ẹni bẹ́ẹ̀ pé:

**Lílé:** *Iṣu oníṣu/2x*
*O ó rẹ̀wọ̀n olóṣù méfa*
**Ègbè:** *Iṣu oníṣu.*

Bí orin bá ti bẹ̀rẹ̀, ìlù á tẹ̀lé e (ìlù bàtá àti dùndún), èrò ìwòran ni elégbé. Bí wọ́n ti ń kọrin, bẹ́ẹ̀ ni wọn a máa jó nígbà tí egúngún náà yó sì máa jó.

Bákan náà, nínú ìjálá aré ọdẹ, ẹnìkan wà tí a mọ̀ gẹ́gẹ́ bí olùṣe eré ti yóó kó àwọn ẹlẹgbẹ́ rẹ̀ jọ gẹ́gẹ́ bí elégbè. Wọn a máa sun ìjálá látí ṣe ayẹyẹ ìgbẹ̀yìn fún ọdẹ ẹlẹgbẹ́ wọn tó ti pa ipò dà. Èyí ni wọ́n ń pè ní ìṣípà ọdẹ. Ayẹyẹ ìṣípà ọdẹ yìí ló ká ọwọ́ àti ẹsẹ̀ olóògbé kúrò nínú gbogbo ètò tó bá kan àwọn ẹlẹgbẹ́ rẹ̀ tó wà láyé. Wọn a máa kọ orin arò lásìkò ayẹyẹ ọ̀hún. Irú orin bẹ́ẹ̀ ni a sábà máa ń kọ lásìkò tí iṣẹ̀lẹ̀ láabi bá sẹ̀. Òun ni a mọ̀ sí ***"Ìrèmọ̀jé orin ìṣípà ọdẹ".*** Bí wọ́n ṣe ń kọrin, bẹ́ẹ̀ ni èrò ìwòran yóò máa bá wọn kọ ọ́, èyí sì tún jẹ́ ọ̀nà kan gbòógì tí wọ́n fi ń gbé ayẹyẹ ọ̀hún lárugẹ.

Alẹ́ ni a máa ń sun ìrèmọ̀jé. Gbogbo ohun èlò ọdẹ tó di olóògbé ni àwọn ọmọ ẹgbẹ́ ọdẹ yóó kójọ sínú igbá tàbí apẹ̀rẹ̀ kan tí wọn yóó sì rù ú lọ sínú aginjù. Ọ̀kan nínú wọn yóó kàn pariwo lójijì pé: *Àràmọ̀jí Eléré!* Àwọn tó kù yóó sì dá a lóhùn pé: *Àràmọ̀ji èlè* tàbí *Alábàárù ooòò"* èyí tó túmọ̀ sí pé wọ́n ń wá ẹnikan tí yóó fínnúfíndọ̀ jọ̀wọ́ ara rẹ̀ láti bá wọn ru ẹrù náà lọ sínú igbó. Wọn a máa mú àwọn ohun èlò ọdẹ tó kú lọ́kọ̀ọ̀kan, wọ́n a máa nawọ́ rẹ̀ sókè, wọn a ní:

**Lílé:** Ẹ̀wù ọdẹ rèé **Ègbè:** Mọ̀jièlè
**Lílé:** Fìlà ọde rèé **Ègbè:** Mọ̀jièlè
**Lílé:** Ṣòkòtò ọdẹ rèé **Ègbè:** Mọ̀jièlè

Wọ́n á gbé ẹrù ọdẹ náà jáde ní ìlú, wọn a máa kọrin bí wọ́n ṣe ń lọ títí wọn ó fi jáde ní ìlú. Ó tẹ́ wọn lọ́rùn kí arúgbó bá wọn gbé ẹrù náà nítorí wọ́n gbàgbọ́ pé ẹni tó bá gbé e kò ní kú, ṣùgbọ́n kò lè níláárí. Ní ibòmíràn, wọn a máa bèèrè lọ́wọ́ Ọ̀rúnmìlà (Ifá) Ẹlẹ́rìí ìpín, wọn a sì ṣe ohun yòówù tí Ifá bá ní kí wọn ṣe.

Ní ti ẹkún iyàwó, ọmọbìnrin tó bá ń lọ sí ilé ọkọ ló máa ń sun ún. Ohùn rẹ̀ máa ń múni lára láti gbọ́ sétí nítorí ó máa ń ṣe àfihàn àìdánilójú bí ó ṣe ń gbìyànjú láti fi ẹ̀dùn ọkàn rẹ̀ hàn. Gẹ́gẹ́ bí Fáníyì (1975, o.i.679) ṣe sọ, ó ní:

*It is a period of uncertainty for the bride, yet it is a period of joy and anticipation because she will soon become independent of parental control and more importantly, she will form a family of her own.*
Ó jẹ́ àsìkò tí kò sí àrídajú bí ohun gbogbo yóó ṣe rí fún ìyàwó, síbẹ̀, ó tún jẹ́ àsìkò ìdùnnú àti ayọ̀ nítorí pé kò níí pẹ́ tí òun pẹ̀lú yóó fi gba òmìnira kúrò lábẹ́ ìdarí àwọn òbí rẹ̀ àti ní pàtàkì jù lọ, òun pẹ̀lú yóó bẹ̀rẹ̀ ìdílé tó jẹ́ tirẹ̀.

Èyí túmọ̀ sí pé wọ́n máa ń kọminú sí kíkúrò tí wọn ń kúrò lábẹ́ ìtọ́ni àwọn òbí wọn àti pé wọn kò lè sọ bí ìdílé tuntun tí wọn ń lọ yóó ṣe rí.

Ẹkún ìyàwó kì í ṣe ohun káríayé. Ó wọ́pọ̀ ní agbègbè Ọ̀yọ́ Yorùbá pàápàá ní àwọn ìlú bíi: Ṣakí, Òkehò, Ìṣẹ́yìn, Ògbómọ̀ṣọ́, Ṣàó àti Ìlọrin. Ohun tó gba àkíyèsí jù lọ ni fífi ẹ̀mí ìmoore hàn àti dídúpẹ́ lọ́wọ́ àwọn òbí rẹ̀ fún ìbíni àti ìtọ́ni wọn. Ọmọbìnrin náà yóo kúnlẹ̀ láti gba ìre àwọn òbí rẹ̀ kí ó tó gbéra lọ sí ilé ọkọ rẹ̀. Bákan náà, yóó lọ sí ilé àwọn ẹbí àti iyèkan bàbá àti ìyá rẹ̀ láti dágbére fún wọn. Ó ṣe é ṣe kí àwọn wọ̀nyí máa fún ìyàwó ní ẹ̀bùn owó tàbí dúkìá, èyí kò túmọ̀ sí pé wọ́n ń tọrọ bárà.

Irú èyí wọ́pọ̀ ní ìlú Ṣàó, ìlú kan lẹ́bàá Ìlọrin nịbi tí wọ́n ti sọ ọ́ di àjọ̀dún pàtàkì tí wọ́n máa ń ṣe lọ́dọọdún. Wọn a máa pe àjọ̀dún náà ní *Àwọ́nga Festival.* Ó jẹ́ àṣà pé kí gbogbo ọmọge tó bá máa lọ sí ilé ọkọ ní ọdún kọ̀ọ̀kan ṣe ìgbéyàwó ní àyájọ́ ọjọ́ àjọ̀dún náà gan-an, (iye yòówù kí wọ́n jẹ́). Ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọmọ ìlú náà níle, lóko àti lẹ́yìn odi ni wọ́n máa ń wálé láti kópa nínú àjọ̀dún náà. Wọ́n á fún ọmọbìnrin tó ń lọ sí ilé ọkọ ní àmì iṣẹ́ àwọn òbí rẹ̀ láti mú lọ́wọ́. Bí àpẹẹrẹ, wọn á fún ọmọ tí bàbá rẹ̀ bá jẹ́ àgbẹ̀ ní ọkọ́. Lásìkò ayẹyẹ náà, àwọn ìyàwó àsẹ̀sẹ̀gbé a máa lọ láti ilé ẹbí kan sí òmíràn láti gba àdúrà lé.nu àwọn ẹbí wọn gbogbo. Nínú ìrìn àjò yìí, bí àwọn ìyàwó méjì bá pàdé lọ́nà, wọn a máa ṣe ohùn sí ara wọn bóyá nípasẹ̀ ewì tí wọ́n fi ń ṣe aárò pé àwọn ń lọ bẹ̀rẹ̀ ìgbé ayé tuntun tí wọn kò mọ bí yóó ṣe rí tàbí nipasẹ̀ orin kikọ láti mú wọn lọ́kàn le. Àwọn ọ̀rẹ́ àti afẹ́nifẹ́re gbogbo ni wọ́n máa ń dúró gẹ́gẹ́ bí èrò ìwòran, wọn a sì máa fún ìyàwó àsẹ̀sẹ̀gbé náà ní oríṣìíríṣìí ẹ̀bùn.

Kò sí pé a ń ya àsìkò kan pàtó sọ́tọ̀ fún kíkọ́ ẹkún ìyàwó bí kò ṣe pé wọ́n á wá ẹnìkan tó ní ìmọ̀ kíkún nípa oríkì ìdílé tàbí ìran wọn tí yóó sì fi kọ́ wọn. Ohun tó tún wọ́pọ̀ nínú ewì wọn ni pé wọn a máa wúre pé kí Olódùmarè bùkún wọn kí ó sì fún wọn ní ọmọ àtàtà. Èyí ṣe kókó nítorí Yorùbá gbàgbọ́ pé orí burúkú ni kí ènìyàn máa bímọ. Bákan náà, wọn a máa wúre kí àwọn rí ojú rere ọkọ àti ti ẹbí ọkọ. Àwọn ọ̀rẹ́ àti ojúgbà ìyàwó a máa kọrin láti fi ìyàwó lọ́kàn balẹ̀ pé kò níí bá àdojúkọ tó ga ju ẹ̀mí rẹ̀ lọ pàdé nílé ọkọ. Ìyàwó yóó dá ewì rẹ̀ dúró lásìkò tí orin bá ń lọ lọ́wọ́. Ní ọ̀pọ̀ ìgbà, àjùmọ̀kọ ni orin tí wọ́n máa ń kọ níbi ẹkún ìyàwó. Àpẹẹrẹ ni èyí:

*Ilé ọkọ ya,*
*Ẹ̀lẹ́ẹ̀dá ìyá rẹ sìn ọ lọ*
*Ilé ọkọ yá.*

Bí èyí tilẹ̀ rí bẹ́ẹ̀, àwọn orin kan wà tí ìyàwó máa ń dá kọ láìsí egbè níbẹ̀. Bí àpẹẹrẹ:

*Bàbá/Ìya mo ń lọ fàdúrà sin mi/2x*
*Kín n má kèṣu kí n má kàgbákò níle ọkọ*
*Bàbá/Ìya mo ń lọ fàdúrà sin mi o/2x*

Bí ìyàwó ṣe ń kọrin, bẹ́ẹ̀ ni omi yóó máa jáde ní ojú rẹ̀. Èyí ló bí pípè tí a pe ewì alohùn náà ní ”*Ẹkún Ìyàwó”*.

A ní láti fi kún un pé àwọn ewì alohùn Yorùbá kan wà tó jẹ́ ti àdúgbò, wọn kì í ṣe ti gbogbo gbòò Yorùbá. Lára wọn ni Yùngbà (ní àdúgbò tàbí agbègbè Ọ̀yọ́), Obitun (ní àdúgbò tàbí agbègbè Òǹdó), Gẹ̀lẹ̀dẹ́ (ní àdúgbò tàbí agbègbè Ẹ̀gbá àti Òǹkò), àti bẹ́ẹ̀bẹ́ẹ̀ lọ; tí olukulùkù sì ní èrò ìwòran tirẹ̀. Èyí ló sún wa dórí ipa èrò ìwòran nínú àgbéjade lítíréṣọ̀ alohùn Yorùba.

## Ipa tí Èrò Ìwòran Ń Kó nínú Àgbéjáde Lítíreṣọ̀ Alohùn

Gẹ́gẹ́ bí a ti sọ ṣáájú, gbígbé lítíréṣọ̀ jáde ní ẹnu a máa wáye nítorí èrò ìwòran wà ni. Èyí túmọ̀ sí pé láìsí èrò ìwòran, kò sí gbígbejáde lítíréṣọ̀ àtẹnuwí. Èrò ìwòran ṣe kókó nínú gbígbéjáde lítíréṣọ̀ alohùn. Pẹ̀lú èrò ìwòran níkàlẹ̀, akéwì, asọ̀tàn, apàlọ́, apohùn, ọ̀ṣèré, yóó lè mọ̀ bí iṣẹ́ rẹ̀ ṣe rí, bí ó ṣe mọ́gbọ́n wá sí. Wíwo àwọn èrò ìwòran lásán mú kí wọn dàbí dígí. Tí ojú dígí bá mọ́ tí ọ̀ṣèré sì rí ara rẹ̀, eré lè máa tẹ̀ síwájú, ṣùgbọ́n tí kò bá lè rí ara rẹ̀, a jẹ́ pé ohun kan ti mẹ́hẹ, eré ọ̀hún kò sì dùn.

Àwọn èrò ìwòran ló ń ṣe kóríyá fún ọ̀ṣèré. Ìhùwàsí àti ìṣesí wọn ló máa ń fún ẹni tó ń ṣe eré ní èrò nípa bí eré rẹ̀ ṣe rí, ó dára ni tàbí kò dára. Bí àpẹẹrẹ, ìgbà tí wọ́n bá pàtẹ́wọ́, tí wọ́n pariwo, tí ẹ̀rí ìdùnnú sì farahàn nínú ìṣe wọn, wọ́n ń sọ fún ọ̀ṣèré pé kí ó máa nìṣó, àwọn ń gbádùn eré rẹ̀ ni. Tí ọ̀ṣèré bá ti rí àwọn àmì wọ̀nyí, yóò ní ìgboyà láti tẹ̀ síwájú. Tí ọ̀ṣèré bá ń sọ̀rọ̀ láìdákẹ́ tàbí tí kò bá fún àwọn èro ìwòran láyè láti dá sí i, iṣẹ́ àwọn èrò ìwòran yóò sọnù pátápátá.

Nípa fífi etí sí àti dídá sí ohun tí ọ̀ṣèré ń sọ, àwọn èrò ìwòran a máa jẹ́ kí ohun tí ọ̀ṣèré ń sọ yéni. Bákan náà, ó tún máa ń fún ọ̀ṣèré ní ìwúrí àti ìgboyà láti ṣe àgbékalẹ̀ iṣẹ́ rẹ̀ lọ́nà tó wuyì ju èyí tó ti ṣe ṣáájú lọ.

Yàtọ̀ fún èyí, èrò ìwòran ni ó dúró gẹ́gẹ́ bí láméyítọ́ fún iṣẹ́ ọ̀ṣèré. Wọn a máa ṣe èyí nípa fífi ìmọ̀sílára àti àríwísí wọn hàn pàápàá nígbà tí eré bá ti ń lọ sí ìparí. Bí àpẹẹrẹ, tí wọ́n bá ti fi ẹ̀rí àìnífẹ̀ẹ́ sí tàbí ẹ̀rí pé eré ti sú wọn hàn, a kò lè fi wé ìgbà tí wọ́n bá ń pàtẹ́wọ́, tí wọ́n ń jó, tí ariwo ìdùnnú sì gba gbọ̀ngàn eré kan. A nílátí rántí pé kò sí òfin tó de ìgbà tí èrò ìwòran lè kúró ní agbo ere, nítorí náà, àwọn èrò ìwòran lè fi àìní ìfẹ́ sí eré hàn nípa jíjáde kúrò ní agbo/gbọ̀ngàn eré ní ọ̀kọ̀ọ̀kan, ẹ̀jẹ̀ẹ̀jì.

Kíkópa àwọn èrò ìwòran máa ń fún ọ̀ṣèré ní àǹfààní láti lè ronú ohun tó kàn láti sọ àti ọ̀nà àgbékalẹ̀ tí yóó lò láti sọ ọ́. A lè fi àlọ́-onítàn Yorùbá ṣe àpẹẹrẹ. Orin tí wọ́n máa fi ń bọ àlọ́-onítàn láàrin dúró gẹ́gẹ́ bí àsìkò ìsinmi fún apàlọ́. Ní irú àsìkò bẹ́ẹ̀, (bó ti wù kí ó kéré mọ), apàlọ́ á rí ààyè láti ronú ohun tó kàn láti sọ àti bí yóó ṣe gbé e kalẹ̀ lọ́nà tí àwọn èrò ìwòran yóó fi ní ìfẹ́ sí i. Ṣé a kò gbàgbé pé ó ṣe é ṣe kí apàlọ́ méjì ṣe àgbékalẹ̀ àlọ́ kan náà ní ọ̀nà tó yàtọ̀ sí ara wọn pàápàá jù lọ nínú ààtò. Bákan náà ni ọ̀rọ̀ ṣe rí nínú iwì àti ẹ̀sà egúngún, bí ìjálá aré ọdẹ ṣe yàtọ̀ sí ìrèmọ̀jé, bẹ́ẹ̀ náà ni ìyàtọ̀ ṣe wà láàrin iwì àti ẹ̀sà. Wọn a máa kíwì níbi ayẹyẹ ìbílẹ̀, bí ìkómọjáde, ìṣílé, ìwúyè àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ, ẹ́sà pípè ní tirẹ̀ a máa wáyé láti inú igbó ìgbàlẹ̀ ní àsìkò ọdún egungun, nítorí náà ọ̀kan kò dúró fún èkejì.

A ti sọ ṣáájú pé lára èròǹgbà lítíréṣọ̀ ni láti ṣe ìtànkálẹ̀ àṣà àti ìṣẹ̀ṣe àwùjọ, ipa pàtàkì ni èrò ìwòran ń kó nínú àmúṣẹ èròǹgbà yìí. Èrò ìwòran ló ń fún ohun tí onìṣẹ́ ọ̀nà lit́íréṣọ̀ bá gbé jáde ní ìtumọ̀ èyí sì máa ń ṣe àfikún ìrírí ọ̀ṣèré. Wíwà ní ìkàlẹ̀ èrò ìwòran máá ń ṣe kóríyá fún ọ̀ṣeré a sì máa fún un ní agbára láti túbọ̀ ṣe dáradára sí i.

A máa ń lo lítíréṣọ̀ alohùn láti tọ́ka sí àwọn ohun tó ń lọ láwùjọ kí a sì ṣe ìgbéléwọ̀n rẹ̀ pẹ̀lú ìfúnnítumọ̀ láti ọ̀dọ̀ èrò ìwòran. Gbígbéjáde lítíréṣọ̀ lè mú kí èrò ìwòran ronú lórí ìrírí, ìgbàgbọ́, iyì èyí tó lè yọrí sí ìyípadà àdáni ẹnìkọ̀ọ̀kan.

Nínú àlọ́ àpamọ̀, àwọn tó ń fi ìdáhùn sí ìbéèrè àlọ́ ni èrò ìwòran. Kò sí gbèdéke ọjọ orí fún àwọn akópa. Ọmọdé àti àgbà, àwọn ọ̀dọ́ lọ́kùnrin àti lóbìnrin, gbogbo wọn ló lè kópa nínú eré àlọ́. Eré àlọ́ máa ń bẹ̀rẹ̀ nígbà tí apàlọ́ bá ké sí àwọn olùgbọ́ tàbí olùtẹ́tísí àlọ́ rẹ̀ pé: "Àààlọ́ ooooooo" tí àwọn olùgbọ́ sì dáhùn pé "Àààlọ̀ọ̀ọ̀ọ̀". Apàlọ́ yóó sọ àlọ́ rẹ̀ èyí tó sábà máa ń jẹ́ ìbéèrè ní gbólóhùn kan tí kò gùn rárá. Àpẹẹrẹ: *Ìkòkò rúgúdú kẹ̀yìn sígbó".* Ní kété tí apàlọ́ bá ti pa àlọ́ rẹ̀ (àlọ́ àpamọ̀) ni àwọn akópa (èrò ìwòran) yóó ti máa na ọwọ́ wọn sókè pé: "èmí mọ̀ ọ́n", wọ́n a máa gbìyànjú láti jẹ́ kí apàlọ́ pè wọ́n láti wá ìdáhùn ṣókí sí àdììtú ìbéèrè tí apàlọ́ gbé ṣíwájú wọn ní ìlànà ìdíjé láàrin àwọn olùgbọ́ tàbí olùkópa nínú eré àló.

Apàlọ́ yóó pe ẹnìkan látí dáhùn ìbéèrè náà. Apàlọ́ yóó sọ èrò rẹ̀ nípa ìdáhùn ẹnìkan bóyá ó gbà á tàbí kò gbà á. Bí ó bá gbà á, apàlọ́ lè sọ pé kí wọn pàtẹ́wọ́ fún ẹni bẹ́ẹ̀. Tí kò

bá gbà á, apàlọ́ yóó sọ pé “o kò gbà á”. Gbogbo ìṣe wọ̀nyí a máa fi kún adùn tó wà nínú eré àlọ́. Nípa síṣe bẹ́ẹ̀, inú àwọn èrò ìwòran a máá dùn, ara wọn a sì máa yá gágá.

Ninú gbogbo ẹ̀yà lítíréṣọ̀ tí a ní, eré-oníṣe àti ewì ló ní àǹfààní èrò ìwòran tó pọ̀ jù, ṣùgbọ́n àrà ọ̀tọ̀ ni ipa tí èrò ìwòran ń kó nínú àgbéjáde eré-oníṣe Yorùbá. Amérédùn ni èrò ìwòran. Láìsí èrò ìwòran, kò sí eré-oniṣe. A wá lè sọ pé yàtọ̀ fún ẹ̀kọ́ tí a fẹ́ fi eré kọ́ni, nítorí èrò ìwòran ni eré-oniṣe ṣe ń jẹ́ síṣe.

Lásìkò àwọn òṣèré bíi Hubert Ògúǹdé, Kọ́lá Ògúmọ́lá títi dórí àwọn bíi' Ìṣọ̀lá Ògúnṣọlá, (I-Show-Perper), wọn a máa polongo káàkiri ìgboro láti mú kí àwọn ènìyàn wá lọ́pọ̀ yanturu láti wá wo eré wọn. Kò sí àniàni pé wíwà níkàlẹ̀ àwọn èrò ìwòran jẹ́ ọ̀kan pàtàkì lára ohun tí ó ń mú kí àwọn òṣere ní ìfẹ́ sí eré síṣe.

A ti ní àǹfààní láti lọ sí gbọ̀ngàn ìṣeré láti lọ wo eré, a sì ti wo ọ̀pọ̀lọpọ̀ eré tí wọn ń ṣe nínú tẹlifisàn tàbí nínú fọ́ran fídíò, a ti ṣe ìgbéléwọ̀n ipa tí ìmọ̀sílára àwọn èrò ìwòran ń kó lórí ìmúgbòòrò àti ìdàgbàsókè eré-oníṣe Yorùbá. Bí eré bá dùn, bí kò dùn, a lè tipasẹ̀ ìmọ̀sílára àwọn èrò ìwòran mọ̀. Bí eré bá dùn, wọ́n á pàtẹ́wọ́, wọ́n a rẹ́rìn-ín, wọn a sì fi gbólóhùn (ìpèdè) tó dùn ṣe kóríyá fún òṣèré tó bá ṣe dáradára, èyí yóó sì fún irú òṣèré bẹ́ẹ̀ ní ìwúrí látí tún ṣe dáradára sí i lọ́jọ́ mìíràn.

A ti sọ sáájú pé kò yẹ kí aríyànjiyàn wà lórí èrò pé nítorí èrò ìwòran ni a ṣe ń ṣe eré-oníṣe. Àwọn ni ‘adájọ́’, amérédùn àti olùgbéléwọ̀n eré síṣe. Gẹ́gẹ́ bíi lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá tó kù. Iye èrò ìwòran tó bá wá sí gbọ̀ngàn eré ni yóó sọ bí owó tí àwọn òṣèré yóó rí kó jọ yóó ṣe pọ̀ tó pàápàá nígbà tí a ti sọ eré síṣe di iṣẹ́ gidi. Fún ìdí èyí, gbogbo ipá ni àwọn òṣèré yóó sà láti rí i pé wọ́n mú ìwúrí bá èrò ìwòran láti mú kí wọn ní ìfẹ́ si wíwo eré wọn.

Síwájú síi, orin kíkọ ṣe pàtàkì nínú eré-oníṣe. Ọ̀kan-ò-jọ̀kan ni ipa tí orin ń kó nínú eré-oníṣe. Bí àpẹẹre, àwọn òṣèré a máa fi orin pààlà sáàrin eré. Wọn a máá fi orin sòfófó ohun tí yóó jẹ́ àyọrísí eré tí a ń wò. Orin nínú eré-oníṣe máa ń sàpèjúwe ipa tí ìṣẹ̀lẹ̀ inú eré kó lára ẹ̀dá ìtàn. Bí àpẹẹrẹ, orin *“Èrò tí ń ròjéje”* tí Alàgbà Ọládèjọ Òkèdìjí fi ṣidé eré Rẹ́rẹ́ Rún jẹ́ èyí tí a mú láti inú àlọ́ Yorùbá, èyí tó tọ́ka sí pé àwọn ẹ̀dá ìtàn inú eré náà (àwọn tí ọ̀rọ̀ kàn gan an) wà ní ojú- ọ̀lọ́mọ-ò-tó, wọ́n sì ní amójúrí tó pọ̀, wọ́n ń fẹ́ olùrànlọ́wọ́.

Orin a máa sọ ìhà tí ẹ̀dá ìtàn (òṣèré) kọ sí ìṣẹ̀lẹ̀ inú eré. Àwọn èrò ìwòran ni wọ́n dúró gẹ́gẹ́ bí elégbè orin nínú eré-onisẹ. Amérédùn ni orin jẹ́. Lásìkò tí wọ́n bá ń gbe orin, inú àwọn èrò ìwòràn a máa dùn, ara wọn a máa yá gágá wọn a sì máa gbàgbe ìsòro wọn lásìkò náà.

Gẹ́gẹ́ bí a ti sọ ṣáájú, kò sí lájọ àjọ ò kún ni ipa èrò ìwòran nínú àgbéjáde lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá. Òṣèré nílò èrò ìwòran látí rí ẹ̀bùn owó tàbí dúkìá gbà. Kì í ṣe ohun àjòjì pé kí òṣèré yí àkíyèsí rẹ̀ padà sí ẹnikẹ́ni tó bá wọ agbo eré lẹ́yìn tí eré ti bẹ̀rẹ̀. Òṣèré lè kúrò lórí ohun tó ń sọ kí ó sì máa ki oríkì ẹni bẹ́ẹ̀ kí orí rẹ̀ lè wú kí ó sì ná òṣèré ní owó gidi pàápàá tí ó bá jẹ́ ènìyàn tó gbajúmọ̀ láwùjọ. Kò sí àní-àní pé ipò pàtàkì ni Yorùbá fi oríkì sí nínú àṣà àti ìṣe wọn. Àkọsílẹ̀ fi yéni pé kò sí ohun tó pọ̀ jù fún Yorùbá láti fún eléré tó bá mọ oríkì orílẹ̀ dáadáa gẹ́gẹ́ bí ẹ̀bùn.

Ipa èrò ìwòran lápapọ̀ nínú àgbéjáde lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá ni láti ṣe kóríyá fún àwọn òṣèré àti láti mú àyípadà tó lóòrìn bá eré wọn, ṣùgbọ́n fún àwọn òṣèré mìíràn, àkóbá ni àwọn èrò ìwòran máa ń jẹ́, ó sì máa ń kó ìpayà bá òṣèré.

Ó ṣe pàtàkì láti mú un wá sí ìrántí pé ọ̀kan lára èròǹgbà gbígbé lítíréṣọ̀ alohùn jáde ni láti dánilárayá. Nínú síṣe èyí, ipa àwọn èrò ìwòran kò kéré. Kò sí àríyànjiyàn pé wọ́n máa ń fi adùn kún eré. Ìṣe wọn àti ìhùwàsí wọn a máa mú kí agbo eré dùn, kí ó sì wuni. Ìdí nìyí tó fi yẹ kí òṣèré mọ èrò ìwòran rẹ̀ dáadáa. Kò sí ẹ̀rí àrídájú pé púpọ̀ nínú èrò ìwòran ni wọ́n ń kíyèsí ohun tí òṣèré ń sọ bí kò ṣe pé ohun tó jẹ wọ́n lógún ni pé kí wọn dá ara wọn lárayá.

Bí èrò ìwòran bá ṣe pọ̀ sí, bẹ́ẹ̀ náà ni òṣèré yóó ṣe rí ẹ̀bùn gbà sí pàápàá ní agbo eré tí a bá ti fi owó wọlé. Ṣùgbọ́n tí òṣèré kò bá kún ojú òṣùwọ̀n, ó ṣẹ́ é ṣe kí iye àwọn òǹwòran dínkù nígbà mìíràn tí irú òṣèré bẹ́ẹ̀ bá tún fẹ́ ṣeré. Ìwadìí tilẹ̀ fi yéni pé púpọ̀ nínú

àwọn òṣèré ìwòyí, pàápàá àwọn tó ti lórúkọ láwùjọ́ ló máa ń fẹ́ láti mọ irú àwọn èèyàn tí a pè síbi ayẹyẹ kí wọn tó gbà láti lọ ṣeré níbẹ̀. Èrò wọn ni pé bí ipò àwọn tí a pè síbi ayẹyẹ bá ṣe ga sí, bẹ́ẹ̀ ni ẹ̀bùn tí àwọn yóó rí gbà yóó ṣe pọ̀ tó.

A ti ṣàlàyé ní ẹ̀kúnrẹ́rẹ́, ipa èrò ìwòran nínú àgbéjáde lítíréṣọ̀ alohùn nípa fífi lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá ṣe ìgbéléwọ̀n a sì rí i pé ipa àwọn èrò ìwòran kò ṣe é fi ọwọ́ rọ́ sẹ́yìn nínú àṣeyọrí tàbí ìkùnà òṣèré lítíréṣọ̀ alohùn. Èyí ló ṣokùnfà ìdí tí àtúpalẹ̀ ipa àwọn èrò ìwòran fi ṣe pàtàkì ní kíkíyèsí, lára ìgbésẹ̀ tí a máa gbé nínú gbígbáradì fún àgbékalẹ̀ lítíréṣọ̀ alohùn. Ìdí rẹ̀ ni ìwọ̀nyí:

(i). Ó ṣe pàtàkì fún òṣèré láti ni òye èrò ìwòran rẹ̀. Èyí yóó fún òṣèré ní àǹfààní láti rí i pé àkóónú iṣẹ́ rẹ̀ wà ní ìbámu pẹ̀lú ohun tí èrò ìwòran ń fẹ́ tàbí tí wọ́n ń retí.

(ii). Nígbà tó jẹ́ pé èrò ìwòran máa ń yàtọ̀ láti agbo eré kan sí èkejì, ó ṣe pàtàkì fún òṣèré láti mọ̀ pé ìmọ̀ wọn nípa iṣẹ́ rẹ̀ yàtọ̀ sí ara wọn. Mímọ èrò ìwòran máa ń ran òṣèré lọ́wọ́ láti lè gbé èrò rẹ̀ kalẹ̀ lọ́nà tó rọrùn tí yóó sì yé àwọn olùgbọ́ rẹ̀.

(iii). Síṣe àfihàn ìmọ̀ nípa orísun èrò ìwòran àti ohun tí wọ́n fẹ́ yóò ṣe ìgbélárugẹ fún ìgbàgbọ́ wọn nínú òṣèré. Ó máa ń ṣàfihàn òṣèré gẹ́gẹ́ bí ẹni tó ti fi èrò sí ìgbáradì rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí àwọn èrò ìwòran ṣe rí i.

(iv). Mímọ̀ pé ìhùwasí àwọn èrò ìwòran máa ń ran òṣèré lọ́wọ́ láti ṣe ìfúnnitumọ̀ sí ìmọ̀sílára àwọn èrò ìwòran. Èyí yóó fún un ní àyè láti ṣe àtúnṣe tí ó bá yẹ, kí ohun tí ó ń sọ lè túbọ̀ yé àwọn olùgbọ́ rẹ̀. Ohun tí èyí túmọ̀ sí ni pé ìgbéléwọ̀n àwọn èrò ìwòran ṣe pàtàkì fún àgbékalẹ̀ tó ní ìtumọ̀ tó sì jẹ́ iṣẹ́ tí a fẹ́ fi rán sí àwùjọ, ó sì tún ń mú kí àjọṣepọ̀ tó dán mọ́rán wà láàárín èrò ìwòran.

**Àgbálọgbábọ̀**

Àpilẹ̀kọ yìí fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé lítíréṣọ̀ alohùn jẹ́ abala kan gbòógì nínú lítíréṣọ̀ ilẹ̀ Áfíríkà èyí kò sì yọ ẹ̀yà Yorùbá sílẹ̀. A mọ àwọn òṣèré lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá mọ ìjáfáfá nínú eré olukúlùkù wọn. A rí wọn gẹ́gẹ́ bí olùfisọjọ̀ iṣẹ̀ṣe Yorùbá. Síbẹ̀, àgbéjáde iṣẹ́ wọn máa ń wuyì nígbà tí èro ìwòran bá wà ní ìkàlẹ̀. Gẹ́gẹ́ bí olùkọ́ kò ti lè kọ́ni láìsí akẹ́kọ̀ọ́, bẹ́ẹ̀ náà ni àwọn òṣèré lítíréṣọ̀ alohùn kò lè ṣeré láìsí èrò ìwòran.

Ohun tó dunni ni pé lónìí, àyípadà ti dé bá ohun tí a mọ̀ sí lítíréṣọ̀ alohùn láyé àtijọ́. Lónìí, ewì kíké ní ìtagbamgba kò wọ́ pọ̀ mọ́, bóyá lẹ́ẹ̀kọ̀ọ̀kan níbi ayẹyẹ bí ìgbéyàwó tàbi ìsìnkú àgbà, a lè rí àwọn ọ̀jẹ̀wẹ́wẹ́ akéwì Yorùbá kọ̀ọ̀kan tí wọn kò ní ju ìṣẹ́jú péréte lọ láti sọ̀rọ̀. Ọ̀pọ̀ akéwì àtijọ́ ló ti sọ ewì wọn di kíkọsílẹ̀. Ohun tó tún gba àkíyèsí ni pé púpọ̀ ewì ìwòyí ni kò ní ìtumọ̀ kan sàn án. Ní ọ̀pọ̀ ìgbà ohun tí wọ́n ń sọ máa ń yàtọ̀ sí àkòrí ewì wọn.

Bákan náà ni ọ̀rọ̀ ṣe rí nípa eré-oníṣe Yorùbá. Lónìí, púpọ̀ gbọ̀ngàn eré àtijọ́ ló ti di gbọ̀ngàn ijó nígbà tí eré síṣe ti di èyí tí a ń wò nínú fọ́nrán fídíò. Èyí kò fún àwọn òsèré ní àǹfààní láti fojúri kí wọn sì sàkíyèsí ìmọ̀sílára èrò ìwòran èyí tí yóó ràn wọ́n lọ́wọ́ láti mọ irú alébù tó wà nínú eré wọn kí wọ́n sì gbìyànjú láti ṣe àtúnṣe tó bá yẹ. Yàtọ̀ fún ti inú fọ́nrán, ohun tó wọ́pọ̀ lónìí ni eré alákọsílẹ̀ tí a mọ̀ sí eré-onítàn. Kódà púpọ̀ nínú eré-oníṣe àtijọ́ ló ti di àkọsílẹ̀ nínú èyí tí a kò ti lè ṣe àfojúrí ipa èrò ìwòran rárá.

Àpilẹ̀kọ yìí dábàá pé kí àwọn òṣèré ìwòyí bẹ̀rẹ̀ sí rí pàtàkì ipa èrò ìwòran nínu àgbéjáde tàbí àgbékalẹ̀ iṣẹ́ ọnà wọn. Wọ́n gbọ́dọ̀ máa wá gbogbo ọ̀nà láti mú kí àwọn èrò ìwòran pọ̀ sí pàápàá jù lọ lásìkò yìí tí wọ́n ti sọ iṣẹ́ wọn di òwò síṣe. Yóó dára bí wọ́n bá lè gbìyànjú látí ṣe àgbéǹde eré síṣe lórí ìtàgé kí èrò ìwòran pàápàá ba lè ní àǹfààní láti kópa tiwọn.

Ní ìgúnlẹ̀, a gbàgbọ́ pé níwọ̀n ìgbà tó jẹ́ pé àwọn òṣèré lítíréṣọ̀ alohùn ní ipa pàtàkì láti kó nínú mímú àyípadà rere bá àwùjọ, àgbéjáde wọn pè fún àkíyèsí ohun gbogbo tó bá yẹ kí wọn kíyèsí. Ó yẹ kí wọn mú síṣe eré tó bá ìgbà mu ní ọ̀kúnkúndùn.

**Àkójọ Orúkọ Ìwé**


Abimbọla, W. (1975). *Yorùbá Oral Tradition*. Ibadan. University Press.

Abimbọla, W. (1976). *Ifá: An Exposition of Ifá Literary Corpus.* Ìbàdàn: Oxford University Press.

Abimbọla, W. (1977). *Àwọn Ojú Odù Mẹ́rẹ̀ẹ̀rìndínlógún.* Ìbàdàn: Oxford University Press.

Abimbọla, W. (2006). *Ìjìnlẹ̀ Ohùn Ẹnu Ifá - Apá kìnní.* Ìbàdàn: University Press Plc.

Abimbọla, W. (1975). *Ìjìnlẹ̀ Ohùn Ẹnu Ifá - Apá kejì.* Ìbàdàn: University Press Plc.

Faniyi, D. (1975). "Ẹkún Ìyàwó: A Yorùbá Nuptial Chant." In Wande Abimbọla (ed). *Yorùbá Oral Tradition*. Ibadan. University Press.

Akangbe, C.A. (2021): *The role of the audience in oral performance.* https://scispace.com/papers/the-role-of-the-audience-in-oral-performance-4wjypbl1w4

Akinyẹmi, A. (2012), African Oral Tradirtion, Then and Now: A Culture in transition. https://scispace.com/papers/african-oral-tradition-then-and-now-a-culture-in-transition-1knnanv1dt

Finnegan, R. (2012). *Oral Literature in Africa.* Cambridge, Open Book Publisher.

Ogunjimi, B.; Na'Allah, A. (1991). *Introduction to African Oral Literature.* Ilọrin: Unilọrin Press

Ogunlọla, O. D. (2004). "Njẹ́ Àgbọ́sọ ni Ìsàré Yorùbá Bí?" Nínu *ALÓRE: Journal of the Humanities.* 14. 145-160. Published by Faculty of Arts, University of Ilọrin. Unilọrin Press.

Ọlatunji, O.O. (1984). *Features of Yorùbá Oral Poetry.* Ibadan: University Press Plc.



Recebido em: 23/02/2025
Aceito em: 24/06/2025



**Para citar este texto (ABNT):** ÒGÚNLỌLÁ, Ọmọlayọ̀ Dúrótadé. Ojúṣe èrò ìwòran nínú àgbéjádé lítíréṣọ̀ alohùn yorùbá. *Njinga & Sepé:* Revista Internacional de Culturas, Línguas Africanas e Brasileiras. São Francisco do Conde (BA), vol.5, nº Especial I, p.61-70, jan./jun.2025.

**Para citar este texto (APA):** ÒgúnlọLá, Ọmọlayọ̀ Dúrótadé. (jan./jun.2025). Ojúṣe èrò ìwòran nínú àgbéjádé lítíréṣọ̀ alohùn yorùbá. *Njinga & Sepé: Revista Internacional de Culturas, Línguas Africanas e Brasileiras.* São Francisco do Conde (BA), 5 (Especial I): 61-70.